Tọ́jú Rẹ̀ fún Ìkẹ́kọ̀ọ́

Gé e, ká a sí méjì, kó o sì tọ́jú rẹ̀

JÓṢÚÀ

KÁÀDÌ BÍBÉLÌ 1

ÌBÉÈRÈ

A. Báwo ni Jóṣúà àti àwọn ọmọ ogun rẹ̀ ṣe wó odi Jẹ́ríkò palẹ̀?

B. Parí ọ̀rọ̀ Jóṣúà yìí: “Ní tèmi àti agbo ilé mi, . . .”

D. Àwọn orúkọ mìíràn wo ni Jóṣúà ń jẹ́?

98 S.K. — Ọdún tí a ko ìwé tó kẹ́yìn nínú Bíbélì

1 S.K.

Ó gbé ayé ní nìkan bí ọdún 1500 Ṣ.S.K.

4026 Ṣ.S.K. — Ọdún tí a dá Ádámù

JÓṢÚÀ

ÌSỌFÚNNI ṢÓKÍ Ọmọkùnrin Núnì. Ìránṣẹ́ Mósè, tí Jèhófà yàn nígbà tó yá láti jẹ́ aṣáájú Ísírẹ́lì. (Ẹ́kísódù 33:11; Diutarónómì 34:9; Jóṣúà 1:1, 2) Jóṣúà kó àwọn èèyàn Ọlọ́run wọ Ilẹ̀ Ìlérí láìbẹ̀rù. Ó gba àwọn ìlérí Jèhófà gbọ́, ó ṣègbọ́ràn sí àṣẹ Jèhófà, ó sì fi ìṣòtítọ́ sìn ín.

ÌDÁHÙN

A. Ọlọ́run ní kí wọ́n yan, wọ́n sì yan yí ká ìlú náà.—Jóṣúà 6:1-27.

B. “. . .Jèhófà ni àwa yóò máa sìn.” —Jóṣúà 24:15.

D. Hóṣéà àti Jèhóṣúà. —Númérì 13:8, 16.

www.jw.org © 2011 Watch Tower Bible and Tract Society of Pennsylvania